# ÀWỌN ÌLÀNÀ ÌTỌNISỌNÀ

# LÓRÍ

# ÌFIPÁ-MÚ-NI-FI IBÙGBÉ ENI SÍLÈ LÓRÍLÈ ENI

**(Guiding Principles on Internal Displacement – Yoruba Translation)**



UNIVERSITÄT BERN

The Guiding Principles on Internal Displacement have been translated into over 35 languages. The English language edition is the original language in which the Principles were drafted and is the authoritative version for reference.

A copy of the Principles in English can be found at
http://www.brookings.edu/fp/projects/idp/resources/GPsEnglish.pdf

The Principles were translated into Yoruba by Dr. Muhammed Tawfiq Ladan, Ahmadu Bello University, Zaria. (2005)

**OCHA**

# ÀWỌN ÌLÀNÀ ÌTỌNISỌNÀ

# LÓRÍ

# ÌFIPÁ-MÚ-NI-FI IBÙGBÉ ẸNI SÍLÈ LÓRÍLÈ ẸNI

**ÀJỌ ÀGBÁYÉ (UNITED NATIONS)**

***Ọ̀rọ̀ Ìsaájú Sí Àtẹ̀jáde Kejì Àwọn Ìlànà Atónisónà Láti ọwọ́ Àtẹ̀lé-Akowé-Àgbà gbogbo gbò Ẹ̀to Abẹ́lé fún Ẹ̀to Ọmọnìyàn Àti Olùsàkóso Ẹ̀to Ìrànlọ́wọ́ọ Pàjáwìrì fún àwọn ìsẹ̀lẹ̀ ẹ ládojúdé Ọ̀gbẹ́ni Jan Egeland***

Lónìí, àwọn ènìyàn tó lé ní mílíònu méèédógbòn, ní àwọn orílè-èdè bíi àadóta kaàkiri àgbayé, ni rògbòdiyàn àti ìtako ètó ọmọnìyàn ti fà tu kúrò ní ibùdo wọn nínú orílè-ède wọn. Iye àwọn ènìyàn béè tàbí jù béè lọ ni a ti pa nípò dà látàrí ìsèlè ìjànbá tó kọjá ipá tàbí ìmò ènìyàn, tàbí àwọn tí irininsé tàbí ohun èèlò ìsé fà.

Àwọn tí a fi ipá òun túláàsì mú fi ilé àti òna wọn sílè, àwọn tí ogun abélé ti sọ di ìsánsá àti alárìnkiri ní orílè ẹ wọn ni àwọn ènìyàn, tí a kì í rántí rárá, tí a kì í sì í kà kún nínú òpòlopò àwọn ìsèlè àjálù káàkiri àgbálá ayé.

Gégé bí Akowé-Àgbà gbogbo gbò, Kofi Anna ti kíyèsí i pé "ìfipá-mú-ni-fi-bùgbé-ẹni- sílè lórílè ẹni jé ìsèlè ẹ ládojúdé tí ó ga jùlọ ní àkókò o wa. Àwọn tí a kó ní papámóra àti fi ipá mú kúrò níbùgbé wọn lórílè wọn jé àwọn tí ó wà nínú ewu tó burú jùlọ nínú ìran ọmọ ènìyàn".

Kíkọbiarasí ìdáàbòbò àti ìrànlówó àìní àwọn tí ìsèlè òjijì ti fi ipá mú fi ibùgbé e wọn sílè lábélé jé òkan lára kókó pàtàkì tó jé ìpèníjà fún àwùjọ ọmọ adáríhurun lónìí.

Nínú òrò ìsaájú sí àtèjáde àkókó, àwọn ìlànà ìtónisónà, olóògbé Sergio Vieira de Mello mú kí Àjọ Àgbáyé (UN) dojú agbára rè kọ òrò àwọn tí a ti mú kúrò ní ibùgbé e wọn pèlú ipá lórílè-ède wọn.

Gégé bí Olùsàkóso Ètò Ìrànlówó ọ Pàjáwìrì fún àwọn ìsèlè ẹ ládojúdé, èmi pàápàá ti mú gbígbélárugẹ àti ìsọdimímò lágbàáyé, ìdàámu àwọn tí ìsèlè òjijì ti mú kí wón sá fi ibùgbé e wọn sílè ní ìlu wọn àti láti wá ètò àti dín ìnira wọn kù kó lékè lórí àwọn èrò mi.

Àwọn Ìlànà Ìtónisónà lórí ìfipá-mú-ni-fi-bùgbé- ẹni- sílè lórílè ẹni, tí a se lábé àtìléyìn Òmòwé Francis Deng, jé ohun èlò pàtàkì tó ń pèsè àtìléyìn àti ònà ìbójútó fún ìrànlówó àti ìdáàbòbo àìni àwọn tí ìsèlè pàjáwìrì ti mu fi ibugbe mú fi ibùgbé e wọn sílè lábélé nílùú wọn.

Inú ùn mi dùn láti fi ìwé yìí sóde pèlú ìgbàgbó pé yóò jé ìrànlówó aseémúlò fún gbogbo àwọn akópa nínú òrò ọmọnìyàn.

Osù Òwèwè, 2004.

## NÍ ÌRÀNTÍ

***Òrò Ìsaájú Sáwọn Ìlànà Atónisónà Láti ọwó Àtèlé-Akowé-Àgbà gbogbo gbò fún Èto Abélé fún ilé isé tó ń bójútó ìgbé ayé rere ọmọnìyàn, Ògbéni Sergio Vieira de Millo.***

Àwọn àjọ tó ń bójútó ìgbé ayé rere ọmọnìyàn ń kíyèsí ìdàámu àwọn tí a ti fipá mú kúrò níbùgbé e wọn lórílè wọn ààrò, èyí tó kan àwọn ènìyàn tó lé lógún un mílíònù jákèjádò àgbálá ayé. Bí ó tilè jé pé ìdáàbòbò àwọn tí ìsòro, ìsèlè àìròtélè sọ di aláìníbùgbé mó jé ojúse Ìjọba Àpapò, Ìpínlè àti ti Ìjọba Ìbílè wọn tó kàn wón gbòngbòn lakòókó; síbè, ó se pàtàkì fún Àjọ Àgbáyé (UN) láti wá ònà tó ye jù láti sa ipá a rè láti wá ààbò àwọn tí òrò kàn nínú un rògbòdìyàn, ìpayà àti àìfòkànbalè. Bákan náà ni a gbódò sètò ìrànlówó ní ònà tí yóò mú kí ààbò àwọn aláìníbùgbé mó wònyí po sí i.

Láàárín ètò ti Àjọ Àgbáyé (UN), àwọn ìgbésè tó níláárí ni a ti gbé láti mú kí ìdáhùn sí àìni àwọn tí ìsòro abélé lé kúrò ni ibùgbé e wọn wà ní àsìkò tó yẹ jùlọ. Ìgbìmò tó wà fún Àjo Àsepo (The Inter-Agency Standing Committee, IASC) ti fi mí se asojú fún ohun gbogbo tó jẹ mọ rògbòdìyàn abélé àti ìfipá léni kúrò ní ibùgbé ẹni láàárín Àjọ Àgbáyé (UN). Ní síse isé yìí, mo ti fara mi jìn fún mímu apá Àjọ Àgbáyé (UN) lápapò gbòòrò sí i láti dásí òrò àwọn tí àjálù abélé wọn ti so di Lárìnka, àti láti bójútó ìsàkoso àti pípín àwọn ojúse òun ìrànlówó tó tó fún àwọn àjọ tó ń sisé wònyí.

Ní oríta yìí, mo faramó ètò Asojú Akòwé-Àgbà gbogbo gbò nípa fífi Ìwé Ìléwó Àwọn Ìlànà Ìtónisónà lórí ìfipá-mú-ni-fi-bùgbé- ẹni- sílè lórílè ẹni látàrí ogun abélé síta. Àwọn Ìlànà Ìtónisónà wònyí tó dá lórí òfin àgbáyé lórí bójútó ìgbé ayé rere fún ènìyàn àti àwọn ohun èlò ètó ọmọnìyàn, ni yoò dúró bi òsùnwòn àgbáyé láti tó àwọn ijọba àti Àwọn Àjọ Ìgbé Ayé Rere àti idàgbàsókè ọmọnìyàn láti sètò ìrànlówó àti ààbò fún àwọn ti rògbòdìyàn abélé ti sọ di aláìnílé.

Gbogbo ara ni Ìgbìmò tó wà fún Àjo Àsepo (The Inter-Agency Standing Committee, IASC) fi ti Àwọn Ìlànà Ìtónisónà léyin, o sì ti rọ àwọn ara wọn láti pín in pèlu àwọn Ìgbìmò Alákòóso wọn àti àwọn òsìsé wọn, pàápàá jùlọ, àwọn tó wà lénu isé náà, láti ri i dájú pé a se àmulò Àwọn Ìlànà wònyí nínú ìse wọn gbogbo lórí àwọn tí a fi ipá sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn.

Mo ní ìgbàgbó pé Àwọn Ìlànà Ìtónisónà le kó ipa ńlá ní sísíniníyè sí àìní àwọn tí a fi ipá sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn, nípa wíwa àtìléyìn láàárín Àjọ tó ń wá ìgbé ayé rere ọmọnìyàn; àti ní riran àwọn ará to wà lénu isé lówó láti wá ojútùú sí ìsòro ààbò àti ìrànlówó àìní àwọn tí ìsòro òun wàhalà sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn lórílè e wọn. Àwọn Ìlànà wònyí yóò sì tún ran àwọn ìjọba lówó ní pípèsè fún ààbò àti ìgbé ayé ìdèra fún àwọn ènìyàn an wọn tí a fi ipá sí nípò padà.

Mo lérò pé enìkòòkan yín yóò sisé láti rí i pé Àwọn Ìlànà Ìtónisónà pèlú ìmúsẹ wọn di mímò fún òpò ènìyàn, kí ète àtimú idàgbàsókè bá ipò àti ìhùwàsí àwọn ènìyàn tí a fi ipá sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn má baà forí sánpón.

Osù Òkùdú, 2001

---

** Ògbéni Sergio Vieira de Mello jé Asojú Akòwé-Àgbà gbogbo gbò ní órílè ède Iraq nígbà tí àgbá ìbọn pa òun àti àwọn òsìsé Àjọ Àgbáyé (UN) mókànlélógún mìíràn ní ọjó kọkàndínlógún osù kẹjọ (Osù Ògún) 2003.*

**Òrò Ì*fáàrà* *láti ẹnu Asojú Akòwé-Àgbà gbogbo gbò lórí Àwọn èniyàn tí a fi ipá sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn*** **ní** ***órílè e wọn.***
***Ògbéni Francis M. Deng****

Ìsòro ńlá tó ń dojúko *Àwùjọ* Àgbáyé ni ààbò àwọn èniyàn tí a fi ipá fà tu kúrò lórílè e wọn n*í*pas*è* ìja àjàkú akátá, àwọn r*í*rú òfin ètó ọmọnìyàn lá*ì*b*ì*k*í*tà àti àwọn isèlè ẹ ládojúdé mìíràn tí kì í mú inú ẹni dùn, sùgbón tí wọn kò fi órílè ède wọn sílè. Ó férè jé pé ní gbogbo ìgbà ni wón ń jẹ ìyà ìt*è*mér*è*, ìf*è*tó- ẹni -dunni, ìpónnilójú àti ìpanitì. Láti bá ìp*è*nijà yìí pàdé, ni a se gbé Àwọn Ìlànà Ìtónisónà lórí ìfipá-mú-ni-fi-bùgbé- ẹni- sílè lórílè ẹni jáde.

Àwọn Ìlànà náà se àfihàn àwọn ètó àti òté à*ì*gbọdò-máse tó níí se pèlú ààbò àwọn tí a fi ipá sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn, ní àwọn ìgbésè kòòkan tó wà nínú ìfipá-mú-ni-fi-bùgbé- ẹni- sílè lórílè ẹni. Won pese aabo kuro lowo ifipa-muni-kuro ni bugbe eni lainidii, eredi fun idaabobo ati iranlowo lakooko ifipa-muni-kuro nibugbe eni; ati lati seto ifokanbale to daju fun ipadabo ailewu, itunni-fi-pada-sibugbe ati igbani-pada sawujo. Bi o tile je pe won ki i se ohun elo kan-n-pa, won si wa ni ibamu pelu ofin eto omoniyan ati igbe aye rere omo eniyan lagbaaye, won si jo ofin to wa fun awon to sa kuro lorile ede won fun aabo.

Leyin opolopo odun ni a to le gbe awon ilana wonyii jade ni ilepa ise ti a gbe le mi lowo ni odun un 1992 lati owo o Ajo Ile Ise to wa fun Eto Omoniyan ati Igbimo Asofin Gbogbo gboo. Ni ibere pepe, a so fun mi lati fiyesi awon ohun to n fa ifipa-muni-fi-bugbe-eni-sile labele àti àbájáde rè, ip*ò* àwọn tí a fi ipá mú fi ibùgbé e wọn sílè lábélé nínú *ò*fin àgbáyé, bí a se ń bá àìni wọn pàdé tó nínú ètò tó wà nílè báyìí, àti àwọn ònà láti fi mú kí ààbò àti ìrànlówó fún wọn pò si. Ààbò ìrànlówó nínú àgbáyé ètò ọmọnìyàn idàgbàsókè pàdé ìgbésè ìjọba àgbékalè mìíràn ìdáàbòbò rògbòdìyàn látàrí

Fún ìdí èyí, àwọn ohun tó jẹ́ gbòógì isẹ́ mi ni láti se àgbékalè àwọn *ò*fin àti ìgbìmò fún àwọn tí a fi ipá mú fi ibùgbé e wọn sílè lábélé àti ìrìnàjò sí àwọn órílè èdè láti bá àwọn ìjọba àti àwọn mìíràn tí òró kàn fikùn lukùn lórí òrò àwọn tí a fi ipá mú fi ibùgbé e wọn sílè lábélé. Ní ìfọwọ́sowọpò pèlú àwọn am*ò*fin àgbáyé kan, mo se àyèwò bí àwọn tí a fi ipá sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn se gba ìdáàbòbò sí lábé òfin àgbáyé, mo sì gba 'Àtòjo àti Àtúpalè Àwọn Ìlànà Òfin' (Compilation and Analysis of Legal Norms, E/Cn.4/1996/52/Add.2). Ìwídìí náà sàwárí pé bí ó tilè jé pé *ò*fin tí à ń lò lówó fààyè tó pò fún àwọn tí rògbòdìyàn sí nípò padà kúrò ní ibùgbé e wọn, ó sì ku òpò ibi tó se kókó tó ti kùnà láti pèsè ìdí fún ààbò àti ìrànlówó wọn. Látàrí èyí, Àjọ àti Ìgbìmò Asòfin Gbogbo Gbòò rò mí láti se Ìlànà Ètó tó yẹ fún àwọn tí a ti fipá mú kúrò nínbùgbé e wọn. Èyí ló bí àkókọ Àwọn Ìlànà Ìtónisónà tí ó se àtúnkọ àwọn àwọn tó ti wà nílè, èyí t ó gbìyànjú àtisàlàyé àwọn ibi tó rújú àti láti dí àwọn àlàfo tó wà.

Léyìn tí mo fi Àwọn Ìlànà Ìtónisónà fún Àjọ (Commission) ní ọdún 1998, Àjọ fọwósí ìpinnu nípa kíkíyèsí Àwọn Ìlànà Ìtónisónà àti àwọn Èrò inú mi tí mo kọ sílè gégé bí *Asojú Akòwé-Àgbà gbogbo gbò* láti lò wón nínú ìfòrò-jomitoro-òrò tó ń lọ lówó láàárín èmi pèlú àwọn ìjọba àti gbogbo àwọn ti àsẹ tí a fi fún wọn àti isé jẹ mó àìní àwọn tí a fi ipá mú fi ibùgbé e wọn sílè lábélé. Àjọ náà tún sàkíyèsí àbájáde Ìgbìmò tó wà fún Àjọ Àsepò (IASC), tí ó ti téwó gba Àwọn Ìlànà náà, tí ó sì ti rọ àwọn ọmọ ẹgbé e rè láti pín in pèlú Àwọn Ìgbìmò Alásẹ àti àwọn òsìsé, ni pàapàakì, àwọn tó wà lénu isé náà, àti láti lò wón nínú isé ẹ wọn fún àwọn tí a fi ipá mú fi ibùgbé e wọn sílè.

Ó y ẹ k í Àwọn Ìlànà Ìtónisónà lè fún àwọn ìjọba, àwọn Aláṣẹ mìíràn tó dáńtó, àwọn Ẹgbẹ́ tí ìjọba kó jọ ati àwọn Ẹgbẹ́ Aládàáni (NGOs) tí kìí se ti ìjọba ní ìtónisónà aseémúlo tí kò lẹ́gbẹ́ nínú isé wọn pèlú àwọn ènìyàn tí a ti fipá mú kúrò níbùgbé e wọn. Èrò mi ni pé a óò pín wọn fún gbogbo mùtúmùwà, a ó sì se àmúlò wọn gidi ní pápá.

Osù Òkùdú, 2001

---

**Ni ilepa ebe Eka Ajo Agbaye (UN) to wa fun eto omoniyan ni ojo kokanlelogun osu kesan an (Osu Owewe) odun un 2004, Akowe Agba Gbogbo Gboo Kofi Anna yan Ojogbon Walter Kalin gege bi Asoju re lori Eto Omoniyan fun awon ti a fipa mu fi ibugbe won sile labele lorile won. Ni ipo re titun, Ogbeni Kalin ni o ropo Francis M. Deng, eni ti o ti je Asoju Akowe-Agba Gbogbo Gboo fun awon eniyan ti a fipa si nipo pada kuro ni ibugbe won lati odun 1992 titi di opin saa re ni osu keje odun 2004.*

## AWON ILANA ITONISONA LORI IFIPA-MUNI-FIBUGBE-ENI-SILE LAAARIN ORILE EDE ENI

## IFAARA – OWOJA ATI EREDI

1. Awon Ilana Itonisona wonyi koju ni pato si aini awon ti a fi ipa mu kuro ni ibugbe won lorile ede won kaakiri ni agbaala aye. Won se eto ati igbowo awon to nii se pelu idaabobo awon eniyan ti ti a fipa si kuro ni ibugbe (aaye) won ati fun aabo pelu iranlowo won ni asiko ti won n foju wina ajalu to de ba won; bakan naa ni o se afihan ipadabo saaye, itun-nifi-pada-sibugbe ati igbani-pada-sawujo.

2. Fun idi awon Ilana wonyi, awon ti a fipa si kuro ni ibugbe won ni awon eniyan tabi agbajo eniyan ti a fi ipa mu ki won sa kuro ni bugbe tabi fi ile won tabi ibi ibugbe won sile, ni pataki nitori ayorisi tabi lati dena ipa ti ajalu le fa, iwa ipa to gbode kan, aibowo fun awon eto omoniyan tabi awon ajalu, yala, afowofa omo eniyan tabi eyi to koja oye tabi agbara eda. Gbogbo awon wonyi ni won si wa lorile ede won, ti won ko tii koja akamo (aala) orile ede won.

3. Awon Ilana wonyi se afihan, won si wa ni ibamu pelu awon ofin eto omoniyan lagbaaye ati awon ofin to ro mo igbe aye rere omoniyan lagbaaye. Won pese itoni fun:

(a) Asoju Akowe-Agba Gbogbo Gboo lori awon eniyan ti a fi ipa si nipo kuro ni ibugbe won ni ile won lati se isee re;

(b) Awon orile ede nigba ti won ba dojuko isoro ifipa-leni-kuro-nibugbe-eni labele lorile eni;

(d) Awon alase to ku, elegbejegbe, olodanni, ninu ibasepo won pelu awon eniyan ti a fi ipa si nipo pada labele; ati

(c) Awon egbe ti ijoba ko jo pelu awon egbe aladaani ninu ijiroro won lori ifipa-sini-nipo-pada labele.

4. Awon Ilana Itonisona wonyi ni o gbodo di pinpin fun gbogbo mutumuwa, ki a si se amulo won ni bo se to ati bo se ye.

IPIN KIN IN NI: AWON ILANA GBOGBO GBOO

## *Ilana kin in ni (1)*

1. Awon eniyan ti a fi ipa si nipo pada kuro ni ibugbe won yoo je anfaani ni kikun ati laisegbe, iru awon eto ati ominira kan naa labe ofin abele, ti orile ede ati ti agbaaye gege bi awon yooku ti ko si ninu iru ipo yii ni orile ede won. A ko gbodo se iyasoto tabi ojusaaju si won ni jije anfaani etoketoo tabi ominirakominira latari pe a ti fipa mu won kuro nibugbe won.

2. Awon Ilana wonyii ko ni etanu si awon ofin agbaye to ro mo esun odaran, ni pato, eyi to nii se pelu ifinufindo pa eya tabi awujo kan run, riru ofin tabi oran dida nipa tite ofin to je mo omoniyan ati ogun loju.

## *Ilana Keji (2)*

1. Gbogbo awon alase, elegbejegbe ati olodanni ni yoo pa awon ilana wonyi mo laise akasi ipo won ninu ofin, a o si se amulo awon ilana yii laise iyato ti o le panilara kankan. Ipamo tabi imulo Awon Ilana wonyi ki yoo ba ipo ofin awon alase, elegbejegbe tabi olodanni kankan ti oro kan.

2. A ki yoo tumo Awon Ilana wonyi gege bi eyi to le se idanilowoko, iyipada tabi ibaje awon ipese eyikeyii ninu awon eto omoniyan agbaye tabi awon irinse ofin agbaye lori igbe aye rere fun omoniyan tabi awon eto ti a fi fun ni labe ofin abele. Ni pato, awon ilana wonyi ko ni etanu si eto lati wa ibi aabo ni orile ede miiran.

## *Ilana Keta (3)*

1. Olori ise ati ojuse awon alase orile ede ni lati wa aabo ati iranlowo lati gbe igbe aye rere fun awon eniyan ti a fi ipa si nipo labele ti o wa ni sakaani won.

2. Awon ti a fipa si nipo ni eto lati beere ati lati gba idaabobo ati iranlowo fun igbe aye rere lati owo awon alase wonyi. A ko gbodo se inunibini si tabi fiya je won fun sise iru ibeere bee.

## *Ilana Kerin (4)*

1. A o se amulo Awon Ilana wonyi laisi eyameya tabi ojusaaju iru yoowu ko je, bii: iran, awo, ako-n-babo, esin tabi igbagbo, iselu tabi ero miiran, orile ede eni, orisun eya tabi awujo eni, ipo eni labe ofin ati lawujo, ojo ori, ailera tabi aherepe, ohun ini, ibi tabi iru awon osunwon miiran bee.

2. Iru awon eniyan kan ti a si nipo labele, bii awon omode, ni pato, awon omo ti ko ni olugbowo kankan, awon aboyun, awon iya olomo wewe, awon obinrin to n se olori ile, awon alaabo ara ati awon arugbo, yoo ni eto si idaabobo ati iranlowo ti ipo won gba ati itoju to nii se pelu aini won ni pato.

IPIN KEJI: AWON ILANA TO NII SE PELU IDAABOBO KURO LOWO IFIPA-SINI-NIPO-PADA

***Ilana Karun-un (5)***

Gbogbo awon alase ati awon akopa agbaye gbodo bowo fun ki won si ri i pe owo wa fun awon ise won labe ofin agbaaye, ninu eyi ti eto omoniyan ati ofin igbe aye rere fun omoniyan wa, ninu ohun gbogbo, ki a baa le dena ati yera fun awon ohun to le yori si ifipa si awon eniyan nipo pada.

***Ilana Kefa (6)***

1. Eda alaaye kookan ni o ni eto si idaabobo kuro lowo ifipa-sini-nipo-pada kuro nile eni tabi ibugbe eni lainidii.

2. Igba ti ifipa-sini-nipo-pada-lainidii ko gbodo waye:

(a) to ba da tabi duro lori 'eleyameya, yiyeju eya kan patapata' tabi iru awon ise bee pelu erongba tabi iyorisi dida aarin awujo awon toro kan ru, yala nitori eya, esin, tabi iran won;

(b) ni akoko ikolu ti ogun, ayafi ti aabo awon alagbada ti o wa nibe ba gba bee fun idi ti o nii se pelu oro awon ologun;

(c) nitori awon akanse ise pataki to gbooro fun idagbasoke, ti kii se ife mutumuwa ni o bi won, ti o si kan won ni dandan;

(c) Nigba ajalu, ayafi ti aabo tabi ipamo ati ilera awon ti oro kan ba gba sisilo; ati

(d) Nigba ti a ba lo o bii ijiya gbogbo gboo.

3. Ifipa-sini-nipo ki yoo pe ju bo se ye lo fun awon idi ti a fi se e.

***Ilana Keje (7)***

1. Ki o to di wi pe a se ipinnu kankan ti yoo fa isi-awon-eniyan-nipo, awon alase ti oro kan yoo ri i daju pe awon ti se agbeyewo gbogbo awon ona abayo miiran lati dena isini-nipo-pada yan-an yan-an. Bi ko ba si ona abayo miiran, a gbodo gbe gbogbo igbese lati din ifipa-sini-nipo-pada ati awon atubotan ibi re ku.

2. Awon alase to n gbe igbese iru isini-nipo-pada yii gbodo ri i daju, niwon bi o se see se mo, pe a pese ibugbe ti o ye fun awon ti a si nipo pada, pe a se iru isini-nipo-pada bee pelu aabo, ounje, ilera, imototo ti o tenilorun, ati pe a ko pin awon molebi kan naa niya.

3. Bi isini-nipo-pada-kuro-nibugbe-eni ba waye yato si igba ikolu ogun ojiji tabi ajalu, a gbodo tele awon ote aigbodo-ma-se wonyi:

(a) eka ase orile ede ti o wa fun atipase iru igbese bee gbodo se ipinnu pato;

(b) a gbodo gbe gbogbo igbese to ye lati fun awon ti a fe e si nipo pada kuro nibugbe won ni iroyin ti o ye kooro tabi alaye kikun lori awon idi ati igbese fun isini-nipo-pada ati, nibi to ba seese, lori i gba-ma-biinu ati itun-ni-fi-sibugbe;

(c) a gbodo wa tabi beere fun iyonda awon ti a fe si nipo pada nibugbee won ni kikun laisi ifipamuni ninu;

(d) awon alase ti oro yii kan yoo lakaka lati je ki awon ti a n si nipo pada, ni pataki, awon obinrin kopa ninu iseto ati isakoso itun-ni-fi-sibugbe miiran fun won;

(e) nibi ti oro igbofinro ba ti yo, awon alase to bofinmu to si kun oju iwon ni yoo se e; ati

(f) eto fun atunse to muna doko, ninu eyi ti atunyewo iru awon ipinnu bee lati owo awon alase onidaajoo wa, ni a oo bowo fun.

***Ilana Kejo (8)***

A ko nii se isini-nipo-pada ni ibugbe eni ni ona to tako eto si iwalaye, ola, ominira ati aabo awon ti oro kan.

***Ilana Kesan-an (9)***

O je orananyan fun awon ijoba orile ede lati daabobo awon omo onile, awon eya ti ko to nnkan, awon agbe alaroje, awon darandaran ati awon egbe miiran to je pe ile won nikan ni won gbokanle fun ounje oojo won kuro lowo ifipa-sini kuro nile eni.

IPIN KETA: AWON ILANA TO RO MO IDAABOBO LAKOOKO IFOJUWINA IFIPA-SINI-NIPO-PADA

***Ilana Kewaa (10)***

1. Eda kookan lo ni eto atorunwa lati wa laaye, eyi ti ofin gbodo daabobo. Ko gbodo si eni ti a gbodo finnufindo fi aye tabi emi re dun. Awon ti a fipa si nipo nile won ni a gbodo daabobo, ni pato, kuro lowo:

(a) Ifinufindo pa eya kan run;

(b) Imoonmo pa eniyan

(c) Ifikanju-pani-laigbejo tabi ipani-lai-nidii; ati

(d) Keeyan deedee di awati pelu ipa, ninu eyi ti ijinigbe tabi itimole lainidii ti ko di mimo, ihalemoni tabi idunkooko-mo-ni to le yori si iku wa.

Ihalemoni tabi iderubani ati iruni-lokan-soke lati se eyikeyii ninu awon ise ti a to soke yii ni a ko nii faaye gba.

3. Ikoluni ati awon iwa ipa (jagidi-jagan) si awon ti a fipa si nipo pada labele (lorile e won) ti won ko lowo tabi tun lowo ninu ija igboro ni a fofin de ni gbogbo ona. Awon eniyan ti a fipa si nipo nile won ni yoo ni idaabobo, ni pato, kuro lowo:

(a) awon ikolu taara tabi aiseyato tabi awon iwa-ipa miiran ninu eyi ti a faaye gba ikolu awon alagbada (eniyan ti ki i se ologun) ni awon adugbo kan ti a ya soto wa;

(b) ifebipani gege bi ogbon ibanija;

(c) lilo o won lati daabobo awon erongba ologun lowo ikolu tabi lati daabobo, roju-rere tabi di ise awon ologun lowo;

(d) kikolu awon ago tabi ibudo won; ati

(e) lilo awon ti agba oloro ti a ri monu ile lati se eniyan lese.

### *Ilana Kokanla (11)*

1. Eda adarihurun kookan lo ni eto si igbe aye alailabuku nipa ti ola ati ti ara, ti opolo ati ti iwa omoluabi.

2. Awon eniyan ti a ti mu fi ibugbe won sile, yala a ti gba ominira won lowoo won tabi ti a ko gba ominira won lowo won, ni a o se idaabobo fun ni pato kuro lowo:

(a) ifipa-bani-sun, isanisaakusaa, idaloro, iwa ika, ifabuku-kan-ni tabi ifiwosi-lo-ni tabi ifiya-je-ni ati awon iwakiwa ati ilokulo ti a se lati fabuku kan ni tabi lati doju ti ni ati awon ise gege bi iwa ipa to koju si ako-n-babo, ni pato, ifipa-muni-sasewo ati iru iwa itenimere bee;

(b) ikoleru tabi imusin igbalode lonakona, bii tita omo foko nigbeyawo, ifimotara-eni-nikan da omo lokowo asewo, tabi ifipa-momo-sise asekara; ati

(c) fifi iwa-ipa se ideyesi tabi iseruba si awon eniyan ti a si nipo pada labele.

Ihalemoni tabi iderubani ati irunilokansoke lati se eyikeyii ninu awon ise ti a to soke wonyi ni a ko nii faaye gba.

### *Ilana Kejilaa (12)*

1. Eda kookan lo ni eto si ominira ati idaabobo. Ko gbodo si enikeni ti a gbodo sadeedee ko lainidii tabi fi si atimole.

2. Lati fi idi eto awon eniyan ti a fipa si nipo kuro nibugbe won mule, a ko gbodo ha won mo tabi de won sinu ago lai ni ominira atijade. Bi iru ahamo tabi atimole yii ba pon dandan ni awon ibi ti a ko ri i ye, ko gbodo pe ju bi o ti ye lo gege bi isele naa ba ti gba.

3. Awon eniyan ti a fipa si nipo kuro ni ibugbe won ni a o daabobo kuro lowo imuni ati atimole eleyameya nitori isininipopada won.

4. A ko gbodo fi awon ti a fi ipa si nipo pada dogo fun idikidii.

### *Ilana Ketala (13)*

1. Ko si ohunkohun to gbodo mu ki awon omo ti a si nipo pada kopa tabi darapo tabi lowo ninu ija igboro.

2. Awon eniyan ti a si nipo pada ni a oo daabobo kuro lowo ifojusaaju muni darapo mo egbe omo-ogun nitori ipo ifipa sini nipo pada kuro nibugbe eni ti won wa. Ni pato, isekise ti iwa ika, ifabukukanni tabi itenimere to fipa muni gba lati darapo mo omo-ogun tabi ki aigba si fiyajeni ni a ko faaye gba ninu ohunkohun.

### *Ilana Kerinla (14)*

1. Enikeni ti a fipa si nipo pada labele ni eto si ominira irinkiri ati ominira atiyan ibi ti o fe gbe.

2. Ni pato, awon eniyan ti a fipa si nipo pada ni eto lati wole si ati jade kuro ninu ago tabi ibugbe titun miiran ti a ko won si.

### *Ilana Keeedogun (15)*

Awon eniyan ti a fipa si nipo pada kuro nibugbe won labele ni:

(a) eto lati wa aabo nibomiran ni orile ede naa;

(b) eto lati fi orile ede won sile;

(c) eto lati wa ibugbe aabo ni orile ede miiran; ati

(d) eto si idaabobo kuro lowo ifipa-dani-pada-si tabi lo gbe nibikibi ti emi, aabo, ominira ati / tabi ilera won wa ninu ewu.

### *Ilana Kerindinlogun (16)*

1. Gbogbo awon eniyan ti a fipa si nipo pada ni eto atimo ohun ti o sele si awon ebi won ti o nu, ati apa ibi ti won wa.

2. Awon alase ti oro kan gbodo lakaka lati se afihan ipo ati aaye ti awon ti a fipa si nipo pada ti a gbo pe won sonu wa. Ki won si fowosowopo pelu Ajo Agbaye to nii se pelu ise yii.

Won ni lati je ki akitiyan iwadii won ati abajade won di mimo fun ibatan ti o sunmo eni to nu.

3. Awon alase ti oro kan yoo lakaka lati gba ati se idanimo awon to ku, gbigba oku won lowo isekuse tabi igekugee, ki won si ri si atitete da oku won pada si eni to sunmo won ju tabi ki won sin won towotowo.

4. Iboji awon ti a fipa si nipo pada labele ni a gbodo daabobo ki a si bowo fun ninu ohun gbogbo. Awon eniyan ti a fipa si nipo pada labele yoo ni eto lati wo ibi ite oku awon eniyan won to doloogbe.

### *Ilana Ketadinlogun (17)*

1. Eda kookan lo ni eto si bibowofun igbesi aye ebi re.

2. Lati fi idi eto awon eniyan ti a fipa si nipo labele mule, awon molebi ti won ba fe wa papo ni a oo gba laaye lati se bee.

3. Awon ebi ti o pinya nipase ifipa-sini-nipo ni a oo tun mu wa papo pada ni kiamosa bi o ba ti see se. Gbogbo igbese ti o ye ni a o gbe lati mu ki itungbepapo ebi bee ya kankan, paapaa julo, ti o ba kan awon ewe. Awon alase ti o wa fun oro yii yoo mu ki iwadii ti awon molebi se ya, won yoo si se koriya, won yoo si fowosowopo pelu ise awon ajo omoniyan to n mojuto itun-ebi-gbero

4. Ara awon molebi ti a ti fipa si nipo pada kuro nibugbe won labele ti a ti de ominira won nipa itimobikan tabi ahamo ninu ago yoo ni eto lati wa po.

### *Ilana Kejidinlogun (18)*

1. Gbogbo awon eniyan ti a fipa mu kuro nibugbe won labele ni eto si igbe aye irorun to kun oju iwon.

2. Bi o ti wu ki o kere mo, laika ohunkohun si, ati laiseyato, awon alase to kun oju iwon yoo pese tabi seto aaye ti ko lewu fun awon eniyan ti a fipa mu kuro nibugbe won si:

   (a) ounje pataki ati omi to see mu ti won je koseemani;

   (b) aabo ati ile gbigbe gege bi ohun koseemani;

   (c) aso wiwo to ye to si ba igba mu; ati

   (d) eto ilera ati bibojuto imototo ilera ayika to se koko.

3. A gbodo se ilakaka pataki lati ri i pe awon obinrin ko ipa kikun ninu eto ati pipin awon ohun koseemanii wonyi.

## *Ilana Kokandinlogun (19)*

1. Gbogbo awon eniyan ti a fipa mu fi ibugbe won sile labele ti won farapa ati ti won saisan ati awon alaabo ara ni yoo gba iru itoju ati aajo ti won fe ni kikun bi o ti se e se mo ati laifale, laisi ifiyatosi ju eyi to nii se pelu ilera lo. Nigba to ba ye, awon eniyan ti a fipa si kuro nibugbe won labele yoo ni aaye si ipese iranlowo ajemokan ati ti awujo.

2. A gbodo se akanse akiyesi ilera awon obinrin, pelu awon ipese ati iranlowo to je mo ilera awon obinrin bii eto ilera nipa ibisi (ibimo) ati iyanju ti o ye fun awon to ti lugbadi ilokulo ibasun ati awon orisi ilokulo miiran.

3. Akanse ifiyesi gbodo wa fun didena awon arun ti n ran ti won si n tanka, ninu eyi ti arun ko-gboogun Eedi wa laaarin awon eniyan ti a fi ipa mu kuro nibugbe won.

## *Ilana Ogun (20)*

1. Eda kookan ni eto si ikasi gege bi eniyan nibi gbogbo labe ofin.

2. Lati mu ki eto awon eniyan ti a fipa mu kuro nibugbe won labele fese mule, awon alase ti oro kan yoo fun won ni awon iwe to ye fun igbadun ati ilo awon eto won labe ofin, gege bi iwe irinna, awon iwe idanimo, iwe eri ojo-ibi ati iwe eri igbeyawo. Ni pato, awon alase yoo ri si itetefunni tabi itunnifun ni awon iwe pataki wonyi ti o sonu ni akoko isini-nipo-pada, laifi awon ote ti ko nilaari bii pipada sibugbe eni owuro lati lo gba awon iwe yii, tabi awon iwe miiran ti o ye lele.

3. Awon obinrin ati awon okunrin lo ni eto ogboogba lati gba iru awon iwe pataki bayii. Won si ni eto lati gba iru awon iwe bee loruko ara won.

## *Ilana Kokanlelogun (21)*

1. Ko si enikeni ti a oo fi awon eru ati awon ohun ini re dun lainidii.

2. Awon eru ati awon ohun ini awon eniyan ti a fipa si kuro nibugbe won labele ni a oo daabobo ni pato, kuro lowo awon ise wonyi:

   (a) ifipako

   (b) ikolu-taara tabi ikolu laiseyato tabi awon iwa ipa miiran;

   (c) lilo lati fi koju ikolu awon ologun tabi lati fi dabobo awon erongba won;

   (d) fifise ohun elo igbesan; ati

   (e) bibaje tabi gbigba eru awon ti a fipa si nipo pada laileto o gege bi ifiyajeni.

3. Eru ati awon ohun ini ti awon eniyan ti a fipa si kuro nibugbe won labele fi sile si ibugbe won aaro ni a gbodo daabobo kuro lowo ibaje, isodi-tara-eni-laileto lainidii ati lona eru laibofinmu, gbigba tabi lilo.

### *Ilana Kejilelogun (22)*

1. Awon eniyan ti a fipa mu kuro nibugbe won labele, boya won n gbe inu ago tabi won ko gbebe, ni a ko gbodo ya soto latari ifipa-sini-nipo-pada won ninu igbadun awon eto wonyi:

   a. awon eto si ominira ironu, eri okan, esin tabi igbagbo, ero ati isoro;

   b. eto si awon anfaani ti ko ni ide lati wa ise ati lati kopa ninu awon eto oro aje;

   c. eto lati darapo mo ati lati kopa, bi ara yooku, laisi idiwo kankan ninu oro ilu;

   d. eto lati dibo ati lati kopa ninu eto ijoba ati ti awujo, ninu eyi ti eto atini aaye si atilo eto yii wa; ati

   e. eto lati banisoro pelu ede ti won gbo.

### *Ilana Ketalelogun (23)*

1. Eda kookan ni eto si eko.

2. Lati mu ki eto awon eniyan ti a fipa mu kuro nibugbe won labele fese mule, awon alase ti oro kan yoo rii daju pe iru awon eniyan bee, ni pato, awon ewe ti a fipa si nipo pada, je anfaani eko ti yoo je ofe ati oranany an ni ile eko alakoobere. Eto eko yoo bowo fun asa, ede ati esin won.

3. Ipa pataki ni a gbodo sa lati ri i pe awon obinrin ati odobinrin ko ipa kikun ati ogboogba ninu awon eto eko.

4. Eko ati awon ohun elo ikoni yoo wa ni arowoto awon eniyan ti a fipa si nipo labele, paapaa julo, awon odo ati awon obinrin, yala won n gbe ninu ago tabi won ko gbe nibe, ni kete ti aaye ba ti si.

## IPIN KERIN: AWON ILANA TO NII SE PELU IRANLOWO OMONIYAN

### *Ilana Kerinlelogun (24)*

1. Gbogbo iranlowo omoniyan ni a oo se ni ibamu pelu awon ilana to je mo iwa rere omo eniyan laisegbe ati laiseyato.

2. Gbogbo iranlowo omoniyan fun awon eniyan ti a fipa mu kuro nibugbe won labele ni a ko gbodo dari sibomiran, paapaa nitori oro oselu tabi oloogun.

### *Ilana Keeedogbon (25)*

1. Olori ise ati ojuse pipese iranlowo omoniyan fun awon eniyan ti a fipa si nipo pada je ti awon ijoba orile ede.

2. Awon Ajo agbaye to wa fun igbe aye rere omoniyan ati awon akopa miiran ti o ye ni eto lati se iranlowo fun awon ti a fipa si nipo pada labele. Iru iranlowo bee ni a ko gbodo ka si igbese aisore tabi iyojuran si eto oro abele orile ede, atipe a si gbodo gba a pelu inu rere. Gbigbawole iru iranlowo bayii ni a ko gbodo moomo daduro lainidii, paapaa nigba ti awon ijoba ti oro kan ko ba lagbara tabi setan lati pese awon iranlowo omoniyan to ye.

3. Gbogbo awon alase (ijoba) ti oro kan gbodo fi aaye gba atimu ki iwole awon iranlowo omoniyan rorun, ki won si faaye gba awon to wa fun ipese iru iranlowo bee kiakia lainidaaduro lati tete ri awon ti a fipa si nipo pada labele.

### *Ilana Kerindinlogbon (26)*

Ohun irinse ati awon eru awon eni to n kopa ninu iranlowo omoniyan ni a gbodo bowo fun ki a si daabobo, won ko gbodo je eni ikolu tabi eni ti a n doju iwa-ipa ko.

### *Ilana Ketadinlogbon (27)*

1. Awon Ajo Agbaye to wa fun igbe aye rere omoniyan ati awon akopa ti o ye, nigba ti won ba n pese iranlowo, gbodo fi aaye to to fun aabo ati eto omoniyan awon ti a fipa si nipo kuro nibugbe won labele, ati ki won si gbe awon igbese ti o ye nipa eyi. Nipa sise eyi, awon Ajo ati awon akopa wonyi gbodo bowo fun awon osunwon ati akojo awon ofin ti o ro mo ihuwasi omoniyan lagbaaye.

**2.** Ipinro ti o saaju yii ko ni etanu (ilodisi) si ojuse aabo ti awon Ajo Agbaye ti a fi ase yii fun, awon ti won le se isee won tabi ki ijoba orile ede beere fun un.

## IPIN KARUN UN: AWON ILANA TO JE MO IPADABO, ITUNPADABO-SI-BUGBE ATI ITUNGBA-PADA-SAWUJO

### *Ilana Kejidinlogbon (28)*

1. Oloori-ise ati ojuse awon alase ti o ye ni lati fi awon ote (amuye) lele, ati lati (ki) pese awon ona sile, ti yoo mu ki awon eniyan ti a fipa si nipo labele le finnufindo pada, ni ailewu ati pelu owo, si ile tabi ibugbe won aaro, tabi lati finnufindo loo pabudo sibomiran lorile ede

ohun. Iru awon alas e bee yoo lakaka lati mu itungba-pada-sawujo awon ti a fipa si nipo pada ti o ti pada bo tabi tun pada sibugbe rorun.

2. A gbodo se ilakaka pataki lati ri i pe awon ti a fi ipa si nipo pada nibugbe won labele ko ipa kikun ninu eto ati isakoso ipadabo, itunpada-sibugbe ati itungba-pada-sawujo won.

### *Ilana Kokandinlogbon (29)*

1. Awon eniyan ti a ti fipa mu kuro nibugbee won ti won si ti pada si ile tabi ibugbe won aaro, tabi ti won ti tun lo tedo sibomiran lorile ede won, ni a ko gbodo pati segbee kan (ya soto) latari pe a ti figba kan fipa siwon kuro nibugbe won aaro. Won ni eto lati ko ipa ni kikun ati logboogba ninu eto gbogbo gboo (lawujo) ni gbogbo ipele ki won si ni eto si anfaani lati odo ijoba.

2. Awon alase ti o ye ni ise ati ojuse lati ran awon ti a fipa si nipo pada labele ti won ti pada ati / tabi tun pada sibudo lowo lati gba awon eru ati ohun ini won ti won fi sile tabi ti a gba lowo won nigba ifipa-sini-nipo-pada. Bi atiri iru awon eru ati ohun ini wonyi ko ba se e se, awon alase to ye yoo pese tabi se iranlowo fun awon eniyan wonyi lati gba isanpada (gba ma biinu) ti o kun oju iwon tabi ona isanpada miiran ti o to.

### *Ilana Ogbon (30)*

Gbogbo awon alase ti oro kan ni won gbodo faaye gba ki won si wa irorun fun Ajo Agbaye to wa fun igbe aye rere omoniyan ati awon akopa miiran ti o ye, ninu imuse awon ase ti a fi fun won, lati le pese itanlowo kiakia ati lainidena fun awon ti a fipa si nipo pada labele ninu ipadabo, itun-pada-si-bugbe ati itungba-pada-sawujo won.

***Translated to Yorùbá byDr.M.T. Ladan, Department of Public Law, Faculty of Law, ABU, Zaria. Nigeria, and Dr. Peter Adeseeni Matemilola.***
***PeterMatems@yahoo.com***
***Department of Yoruba,***
***Federal College of Education, P.M.B. 1041, Zaria, Nigeria.***

*Àà Áá Èè Éé Ìì Íí Òò Óó Ùù Úú Ọọ Ẹ ẹ Ẹ́ẹ́Ả Ọ́ọ́ ń Ń*